ORAN-EDUN AWON HAUSA MOKE NI'LU OYINBO

# IROHIN YORUBA

Ẹṣin Oro Wa— "IWAJU L'ỌPA ẸBITI NRE SI"

**Akiyesi**

A fẹ ki awọn onibara wa ma san owo si apo wa dede, ẹniti ko ba san owo tirẹ, ki o ma yaa l'ẹnu bi a ba da a duro lojiji, ao si gba owo wa lọwọ rẹ.

*OLOTU,*
Irohin Yoruba.

IV VOL. NO. 641 IBADAN, MONDAY, NOVEMBER 20, 1950, OWO IWE IROHIN YORUBA — KỌBỌ KAN (1d)

## ỌLỌLA H. M. FOOT DI GOMINA JAMAIKA: ẸNI-ỌWỌ BIṢỌPU VINING TI ILE DE

### B'ORI PẸ NILẸ A DI IRE

OGBOMỌṢỌ—Ni ọjọ 'Bọ ti nṣe ọjọ kọkandinlogun oṣu to kọja ni okiki kan pe Solomon Adegboiyega Ọlàsoko pẹlu Omidan Adunọla Kẹhinde ṣe igbeyawo ti o kamọmọ. Wa wo o gẹgẹbi ayọ ati inawo ti kun ọkan awọn enia wọnyi:– Sule O. Ọlasoko, Sam O Ọlasoko, Wọye Ibiyẹmi, Gbadebọ O. Ọlasoko, Ajani Ọlasoko, E. Alabi Ọlasoko, Moses Ajamu, Oyeniran, Afọlabi ati gbogbo Emilere patapata.

A ki gbogbo awọn Ẹgbẹ fun are ariya ti wọn ṣe ni ọjọ na. Woyi oṣu mẹsan, ilasa ọmọ o.



ẸNI-ỌWỌ JULỌ BIṢỌPU LESLIE GORDON VINING C.B.E., M.A.

### IJỌ ONITẸBỌMI ṢE ÀJỌDUN ORIN

JOS—Ni ọjọ kẹdogun oṣu kẹwa ọdun yi ni awọn Ẹgbẹ Akọrin Ijọ Baptist Church ilẹ yi ṣe ajọdun ẹgbẹ wọn.

Ni agogo mèji abọ ọsan ni isin na bẹrẹ, Alufa E. O. Agboọla ni o fi adura ṣi ipade na, ẹniti o ṣe alaga ni Ọgbẹni Ànimaṣawun D. Alao ati ọga awọn ajikọdidun ninu orin ọjọ na ni Ọgbẹni J. A. Owolabi.

Awọn enia ti o wa sibẹ ti pọju ki a ma a darukọ wọn lọkọkan lọ. A ki awọn Ẹgbẹ Akọrin na aseyi ṣ'amọdun o.

## Ọran-Edun Hausa Moke

Gẹgẹ bi irohin ti a fun nyin laipẹ yi nipa ipinnu Igbimọ Aṣofin Nigeria lori ọran awọn Hausa pe nwọn nfẹ ki Aṣoju awọn jẹ idaji ki ti Yoruba ati ti Ibo jẹ idaji ninu Igbimọ Aṣofin Nigeria.

Awọn Ijọba wa ti fi eto ati ipinnu na ṣọwọ si Ọgbẹni Ọlọla James Griffiths ti iṣe Alakoso Ijọba ilu Amọna Gẹsi (Secretary of State for the Colonies) fun ayẹwo ati ilọwọsi.

Ni aipẹ yi nigbati nwọn nṣe Ajọ Igbimọ Ipade Ajunmọṣe (House of Commons) ni ilu Oyinbo lohun ni Ọgbẹni Ọlọla James Griffiths sọ fun gbogbo Ajọ Igbimọ na pe on ti fi ọwọ si ipinnu Igbimọ Aṣofin Nigeria nipa eto titun (New Constitution) ti nwọn nṣe, nwọn o si bẹrẹ si i mu gbogbo ipinnu eto na lo ni arin ọdun ti mbọ yi (Middle of 1951)

Gbogbo ipinnu na ni o fi ọwọ si pe o dara ṣugbọn eyiti jẹ pataki ti awa ti Iha Iwọ orun (Yoruba) ati awọn ti ilu Iha-Ila-Orun (Ibo) ni ikunsinu si ti a si nfe atunṣe fun ni ti idaji enia ti Igbimọ Aṣofin wa gba fun awọn ti Iha Ariwa (Hausa) lati ni.



ỌLỌLA H. M. FOOT C.M.G, O.B.E,
Aṣoju Ijọba Nigeria ati
(Chief Secretary to the Govt.)
Ti o di Gomina titun Jamaika.

## Ọlọla H. M. Foot Di Gomina

Ọgbẹni Ọlọla James Griffths ti iṣe Alakoso Ijọba Ilu Amọna Gẹsi (Secretary of States for the Colonies) si kede rẹ pe Alaiyeluwa Ọba Ilu Oyinbo ti fi ọwọ si ipinnu igbega ipo Ọgbẹni Hugh Mackintosh Foot C. M. G., O.B.E ti iṣe Aṣoju Ijọba Nigeria ati Adele Gomina nisisiyi pe o di Ọgagun ati Gomina Ilu Jamaica (Capain-General and Governor-in-chief of Jamaica) dipo Ọgbẹni Ọlọla John Huggin G. C. M.G., M. C.

Ninu ọdun 1947 ni Ọgbẹni yi wa bẹrẹ iṣẹ Aṣoju Ijọba ilẹ yi ni Akoko Gomina Arthur Richards, Ni igbati o gba isinmi lọ si ile ni aseko ti awọn Oluwadi-Ọran nṣe iwadi Ọpẹalaiye ti o ṣẹlẹ ni Enugu ti ẹmi awọn oṣiṣẹ mọkanlelogun lọ sii ni a ti ngbọ finrin-finrin igbega ipo rẹ yi.

Nisiyi ọran na ti wa yanju o, o si ti di mimọ fun gbogbo enia pe Ọgbẹni Ọlọla H. M. Foot ti di Gomina ilu Jamaica. Adura wa ni pe ki Oluwa mu de ọhun ni alafia, Ki o si fi ifẹ wa si ọkan ẹniti nwọn a tun fi rọpo rẹ fun wa o.

## Bisọpu Vining Ti Ile De

EKO—Ni ọjọ 'Ru ti iṣe ọjọ kẹdogun oṣu yi ni Ẹni-Ọwọ julọ Biṣọpu Leslie Gordon Vining C.B.E., M.A. ti iṣe Olori Ijọ "Church Missionary Society" ilẹ yi, ti o ti gba isinmi lọ si ile (Ilu Oyinbo) lati bi ọdun kan nisisiy pade de si ilẹ yi.

Gbogbo aseko ti Ọgbẹni Ẹni-Ọwọ yi lo ni ilu rẹ lọhun ni o fi nranti awọn Ijọ rẹ ni ilẹ yi gẹgẹ bi Oluṣọ-Agutan rere ti i ma ṣe aniyan awọn agbo agutan rẹ, nitoripe, igbakugba ni i ma a ba wọn pejọ, tabi lati ṣe isin pataki pẹlu awọn enia wa ti o wa lọhun.

A si ki Ẹni-Ọwọ na ku abọ ati Ijọ CMS Nigeria ku amojuba Olori Ijọ wọn, ki Ọlọrun fun Ẹni-Ọwọ na ni agbara lati ma a ba iṣẹ rere rẹ lọ pẹlu Ore-Ọfẹ Ọlọrun siwaju ati siwaju.

*FUN ILỌSIWAJU*
Ẹ POLOWO OJA NYIN
SINU IWE
IROHIN YORUBA



Ọgbẹni Ọlọla James Griffiths,
*Alakoso Ijọba Ilu Amọna Gèsi*
(Secretary of State for the Colonies)

OWE: ATARI KI I PỌ NI ỌJA KI A MA MỌ ORI BABA TI O BI NI

